# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VLO XIV NO 887 LAGOS SATURDAY SEP 21—SEPTEMBER 27 KỌBỌ MEJI (2D) 1963.


## Alakoso Ijọba Nigeria:

# Gomina Azikiwe Goke Agba, Republic Soju Emi

EKO — Gbogbo apejo awọn ọmọ ile igbimọ aṣofin l'Eko, ni Ibadan, Kaduna ati Ẹnugu ti fọwọ si iwe ofin ti nwọn fi yan Gomina—agba Ọlọla Dokita Nnamidi Azikwe gẹgẹbi baalẹ alakoso gbogbo Ijọba Alailọba (Republic) Nigeria ni alẹ ana.



...ẹgẹbi iwe ilana Ijọba tuntun na baalẹ alakoso Ijọba yi ni yio ma yan olo-

ri awọn minisita ti a npe

ni Prime Minisita, ọdun marun gbako ni yio si ma ṣe lori aga ipo rẹ ki nwọn to yan ẹlomiran dipo rẹ.

Ki wọn to tọwọ bọ iwe ofin tuntun na ọpọlọpọ awọn ikọ ile igbimọ aṣofin na ni nwọn bu omi ọrọ lu ara wọn loju lori wipe awọn ko fara mọ ọna ti nwọn la silẹ lati yọ baalẹ alakoso Ijọba na ti iwa rẹ ko ba tẹ awọn ara ilu lọrun mọ.

Gẹgẹbi eto iwe ofin Ijọba tuntun na agbara aṣẹ ti Prime Minister ni lo fẹrẹ ju ti baalẹ alakoso (presi-


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


# Ijọba Fun Awon Osise Lowo Ajoyo

EKO—Ni alẹ ana awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe l'Eko ati awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ mẹrẹrin ti o ku ṣe ikede wipe awọn ti ṣe eto tan lati fun gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba ni owo oṣu kan ti nwọn ba ngba lati fi ṣe ajọyọ Ijọba Republic ti a fẹ ṣe ni ọsẹ ti mbọ

Lati bi ọjọ mẹta ni gbogbo awọn osiṣẹ ti bẹrẹsi kigbe wipe awọn fẹ ki wọn fi owo kun owo awọn. Ọrọ na le tobẹgẹ ti awọn oṣiṣẹ fi sọ wipe ti nwọn ko ba fi owo kun owo awọn ajọyọ eto Ijọba Kosọba yi awọn Olotu fẹ ṣe ni ọjọ mẹwa ko ni fi inu didun ṣee.

Awọn osiṣe ni awọn yio fi ada kọri, awọn ko ni lọ si ibi iṣẹ lọjọ na. Nwọn ni awọn ti o ngbalẹ ninu awọn ko ni gbalẹ; awọn ti o ntanna ẹlẹtiriki fun wa ko ni tan an. Nwọn ni ko nse iyẹn nikan, awọn ko ni jẹki ọkọ reluwe rin fun ọjọ mẹta tabi ju bẹ lọ.

Awọn osiṣẹ ni nigbakugba ti awọn ba sọ wipe awọn nfẹ owo ni awọn alamojuto Ijọba ma nsọ wipe ko si ... lapo Ijọba ṣugbọn ... mọ ọna ti nwọn fi owo kun owo awọn oṣelu Nwọn ni ọja kanna ti iyawo awọn oṣelu nna ni iyawo awọ lebira nna.

A gbọ wipe owo yọtọmi ti Ijọba fẹ ya awọn osiṣẹ yi oṣu mẹfa ni nwọn yio fi san an. Nwọn ni awọn fun wọn ni anfani lati gba gbese owo oṣu kan na ki nwọn ba le ri nkan ṣe ajọyọ eto Ijọba Republic na ni ẹkun rẹrẹ ni.

## Oniwasu Nla Kan Mbo Wa Si Nigeria

BOSTON — Alufa oniwasu nla kan ara ilu Amẹrika ti orukọ rẹ njẹ Dokita Howard Thurman ni a gbọ wipe o ti wọkọ, o mbọ wa si ilẹ Nigeria.

Dokita Thurman yi jẹ ọkan ninu awọn alufa oniwasu mejila ti nwọn sọ wipe nwọn ko kẹrọ ninu iṣẹ wọn ni ilu Amẹrika Olukọni ni ni ile ẹkọ giga julọ ni Boston University, o si mọ bi a ti nkọ enia ni iṣẹ iwasu ṣiṣe pupọ.

Oṣu marun gbako ni awọn alamojuto ile ẹkọ ti o gbe ti o gbe ti nṣe iṣẹ tiṣa olukọni na yọnda fun lati fi lọ si irin ajo rẹ yi. On ati iyawo rẹ ni o mbọ wa bẹ wa wo.

Ti o ba de a fi igba diẹ kọ awọn akẹkọ wa ni ile ẹkọ giga ti o wa ni Ibadan lori ẹkọ isin.

Dokita Majękodunmi Ni:

# "O Ye Ki Awa Yoruba Parapo"...

EKC—Ọọlẹ Dokita Moses Adekoye Majękodunmi, ti o figba kan şe alakoso pajawiri fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti o si jẹ ọkan ninu awọn ti o şeşẹ da Ęgbẹ Yoruba Parapọ silẹ ni o ye ki awọn Yoruba parapọ lọkunrin ati lobinrin ki iya ki o ba ma le jẹ wa tọmọ tọmọ.

Dokita Majękodunmi la ọna anfani mefa silẹ ti awọn fi da ĘGBĘ YORUBA PARAPỌ na silẹ, o ni awọn fẹ fi ye gbogbo enia wipe ẹgbẹ na kişe ẹgbẹ oşelu rara, o nfun irẹpọ larin awọn ọmọ Yoruba ni awọn şe daa silẹ.

O ni ko nşe nkan ti o ba ọjọ mu lati ri wipe gbogbo nkan iyi ati ẹyẹ ti awọn Yoruba ti ni lati igba aijọ ti nlọ sẹhin; awọn da ẹgbẹ yi silẹ lati gbe gbogbo ogo awọn Yoruba ga.

Dokita Majękodunmi tun şe alaye wipe ọkan ninu nkan ti awọn fi da Ęgbẹ Yoruba Parapọ na silẹ ni wipe iyi ati ẹyẹ ti awọn Ọba ati awọn ijoye Yoruba ti ni awọn ko fẹ ki nwọn fi ọwọ rọ wọn sẹhin.



O ni ero ti awọn fi da ẹgbẹ na silẹ ni wipe ki a le ma gbe pẹlu irẹpọ pẹlu awọn alabagbe awọn ti kişe ọmọ yoruba ti nwọn wa ni Nigeria ati ni ibomiran kakiri.

Dokita Majękodunmi ni o jẹ nkan ti o ya awọn lẹnu lati ri wipe ko si ẹgbẹ kan ni ilẹ Yoruba ti o le dide lati da si ọrọ ija ti o ti bẹ silẹ larin awọn oşelu ilẹ Yoruba ni Ibadan lati igba kan ti gudugbe na ... silẹ, bẹ bi o ... ba şe

wipe larin awọn ẹya ibilẹ miran ni awọ ti bẹ silẹ bayi awọn ẹgbẹ ibilẹ wọn yio ti dide sii gbogbo rẹ yio si ti pari.

O ni awọn kan ni nigbati ĘGBĘ ỌMỌ ODUDUWA ti wa ko yẹ ki awọn di ẹgbẹ Yoruba Parapọ kan silẹ mọ. Dokita Majękodunmi ni ọrọ yẹyẹ niyi o ni gbogbo awọn ti nwọn nba ara wọn ja yi ọmọ ẹgbẹ Oduduwa ni wọn. O gbogbo agbaiye ni nwọn fi ọrọ Ęgbẹ Majękobajẹ (League of Nations) ti o ja lulẹ ni iwọn nkan bi ọdun marunlelogoji kọ'jọbọn ki nwọn to tun da omiran ti nwọn npe ni Ęgbẹ Agbajọ Agbaiye (United Nations) silẹ, ẹgbẹ na si nşe ribiribi fun ara aiye nisisiyi.

Ọdun mẹfa ni Ijọba Apapọşe ni awọn fẹ fi şe nkan idagbasoke fun ilẹ Nigeria, gbogbo awọn Oyinbo olowo ati onişowo ni o nsara lati wa da işẹ silẹ nilẹ Yoruba nitori bi nwọn ti nri bi nkan ti nlọ si larin awa Yoruba.

Gbogbo nkan aje ti nwọn fẹ dari sọdọ awọn Yoruba ni nwọn ti gbe gba ipinlẹ miran lọ.


# E Polowo Oja Yin

## Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe Losose


## Iyi Yoruba Nlo Sile

Awọn ti nwọn joko, ti nwọn rò ero lati da ĘGBĘ YORUBA PARAPỌ silẹ ni bi ẹ ba şe akiyesi ẹ o ri wipe gbogbo iyi ti awọn Yoruba ti ni lati aijọ ti nlọ silẹ.

Nwọn ni lati igba ti ede aiyede ti de ni ipinlẹ Iwọ Orun gbogbo nkan orire ni nwọn ti ngbe fo awọn yoruba patapata.

Ni ilẹ Nigeria, awọn alamojuto eto işẹ Ijọba Apapọşe ti şe eto lati şe bi gbogbo nkan yio şe ma lọ deede ni gbogbo ipinlẹ kakiri şugbọn nwọn nfi ọwọ rọ awọn ọmọ Yoruba sẹhin.

# Iya Olomo Marun Ngbe Laruge

Ko si nkan tuntun ni oju ọrun — ni ọrọ arabinrin kan ti o bi ọmọ marun ni ikunlẹ kanşoşo ninu ọsẹ yi, obinrin ti o bi awọn ọmọ na ni aya ọkunrin kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Efren De Prieto nilu Venezuela.

Ninu ile awọn abiyamọ ti iya awọn ọmọ na gbe wa ni bale rẹ gbe wọ lọ, ti o si pe alufa kan wipe ki o ba awọn şeto yigi iyawo nitoripe inu on dun pupọ fun ibarun ti iyawo on bi yi.

Ọmọkunrin marun kişe yẹyẹ ki awọn obi tẹ tẹpa mọ şe fun owo ẹba tabi burẹdi loku. Iya Ọlọmọ marun ngbe larugbe.

Fro Ijoba Kos'oba:

# "Olofintoto' Ni Nwon Ko Fi Ye Wa Eleti-Ofe Gun Oke Agba

Awọn Yoruba ni o mbọ, o mbọ, awọn ni a ndẹ dee. O ku ọjọ mẹwa gbako loni ti a o gbe ẹwu tuntun kan wọ awọn tani o da ẹwu na fun wa, boya nkan ti awọ ti o nka iwe yi yio bere niyẹn. Idahun mi ni wipe awọn ti a yan gẹgẹbi aṣoju wa sile igbimọ aṣofin.

## Opa Wahala

Boya o tun le bere wipe iru kini ẹwu na, ẹwu-ominira ni tabi ẹwu-wahala ni idahun yi ni emi OLOFINTOTO ko le dahun daradara nitoripe awọn ti a ran lọ sile igbimọ gẹgẹbi alamojuto Ijọba wa, nwọn ko fi ọrọ ire ati isoro ti o wa ninu IJỌBA KOS'ỌBA (REPUBLIC) tuntun ti nwọn fẹ gbe fun na na y: wa rara.

Awọn ni awọn lọ sọhun awọn ni nwọn ti ọhun bọ. Bi a ba da gbogbo ara ilu Nigeria si ọna'mẹrin ko da mi loju wipe awọn ti nwọn le sọ ki ni anfani ti ao ri gba ninu Ijọba Kos'ọba yi to da kan. Gbogbo awọn ti o fẹ ki eto ijọba tuntun na ko wa saiyenie kiakia ko ju awọn oṣ lu aṣoju ti a yan sile igbimọ lọ, nitori ọwọ epo ti nwọn yio ri pọnla nibẹ.

## A So Ipanpa

Gbogbo atunṣe ofin ilu ti nwọn ntun ṣe ni pajawiri, kọrọ lare ile ni nwọn nṣee, nwọn ko fi han awọn ara ilu rara. O dabi ẹni wipe awọn asoju wa so ipanpa le awa ara ilu lori wipe ki awọn "jẹ niye" ti awọn ba le jẹ ki nọ twon

(wo yoku loju ewe kẹfa

---

# Obabinrin Ilu Gesi Tun Loyun

LONDON—Irohin kan pataki ti a gbọ lati agbala ile Ọba Obinrin ilu Gẹsi ni London ni eyiti awọn akọwe asoju Ọba na gbe jade wipe Alaiyeluwa Ọba Elizabeth Keji wa ninu oyun nisisiyi, oyun na si mba a nilẹ ko ni le ma sare sihin sare sọhun mọ.

Gẹgẹbi ikede awọn akọwe Ọbabinrin na, nwọn ni oyun na ulọ si bi oyun oṣu marun ati pe ninu oṣu ọdun tuntun (January) 1964 ni yio bi ọmọ inu rẹ nitori eyi Alaiyeluwa na ni lati fara sọwọ.

Iyẹn ni wipe ko ni saye fun un mọ lati ma lọ si ibi ariya kankan lode mọ titi yio fi bi tibi tire. A gbohun iya, a gbohuu ọmọ.

---

# Eka Oro

## Ayiluka Ti Okun Fun Irohin Aladun Ati ero Isiri Loju Ewe Karun

**BE TALLER**
Inrease your Heigth. Details free. Add :— C.T. Hospital Azad Market. Delhi 6, India.

---

# Lati owo Murray O A Okodabi

E Enia lasan pọ, oju igbẹ, ẹni rere wọn ju oju lọ.
L Lakalaka ko ṣe fi l'aja, ọmọ egun ko ṣe gbe ṣire.
E Eyi ko to fo, eyi ko to fo, fila imale fi ku pẹki.
T Tani mẹhin ọla?
I Ile ni iku wa ẹran ajoji, oyan mọpin ẹran Olugbode.
Ọ Opẹrẹkẹtẹ ndegba, inu adamọ nbaje a di baba tan, inu nbi wọn
F Fila ko dun bi ki a mọ de, ṣokoto ko dun bi k a mọ wọ.
Ẹ Ẹni a gbe gun ẹlẹdẹ, iwọn ni ki o yọ mọ, ẹn gun ẹsin ile l'o mbọ.

---

Agbako Ori Ede!

# Awon Janduku Oyinbo Ju Bombu Oloro Si Arin Sosi Enia Dudu

BIRMINGHAM (ALA) — Agbako ori ede ma tun niyi o! awọn janduku Oyinbo alawọ funfun ilu Amẹrika ti nwọn ni awọn ko fẹ ri awọn alawọdudu sọju ni a tun gburo wipe awọn ju bọmbu oloro kan sarin ṣọṣi ti awọn enia-dudu gbe njọsin lọwọ ni ijeje.

A gbọ wipe ko si nkan ti o fa ọrọ ju iwa ikorira ti o ti wa latin awọn Oyinbo alawọ-funfun ilu Amẹrika ati awọn enia-dudu ti o wa nibẹ lọ. Lati ọjọ alaiye ti da aiye ni awọn alawọ funfun ti nhu iwa wipe awọn lọmọ onilẹ, ẹru ni awọn enia dudu jẹ s'awọn.

Nwọn ni ko si nkan ti o le da awọn pọ pẹlu wọn rara. Awọn enia dudu ti o wa ni Amẹrika si nsọ fun wọn wipe ko si ẹru kan mọ ni aiye ti a wa yi, nwọn ni bi a ti bẹru ni a bọmọ, gbogbo ibi ti awọn awọn alawọ-funfun yi ba nrin si ni ilu ni awọn na ni ẹtọ lati rin si

Ọpọlọpọ enia ni bọmbu oloro ti nwọn ju si Ṣọṣi na pa, enia awọn ti nwọn gbe loku jade nlọ bi enia mẹwa ogbọn. Gbogbo mọ to aọọ kẹlẹ ti nwọn wọ wa ninu Ṣọṣi na ni bọmbu bajẹ patapata.

A tun gbọ irohin kan lati ilu Alabama na wipe wiye awọn yin ibọn pa ọmọ enia-dudu kan ti o nrin lọ nitajeje rẹ; gbogbo iwa buruku ti nwọn si awọn alawọ-dudu yi ni o mba Baalẹ ilu Amẹrika, Ọgbẹni Kennedy ninu jẹ, o si ti ṣmera lati ko awọn soja lọ si ilu na.

# ELETI–OFE

( A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL.XIV. NO 887 SATURDAY SEPT 21 - SEPT 27 1963


## ORO OLOTU:

# Nibo Ni Awa Yoruba Ngba ?

A ri iwe kan gba lati ọdọ ẹnikan ninu awọn ọkawe wa lati Oke Bode ni Ibadan ninu ọsẹ yi ti o kan saara si awọn ọmọ Yoruba, awọn bi Dokita Akerele ati Dokita Adekoye Majẹkodunmi, ti nwọn ri bi igbesi aiye awa ọmọ Yorwba ti nlọ, ti nwọn da a ni imọran wipe o yẹ ki a parapọ ti awọn ẹnikan si mbu atẹ lu ọrọ wọn.

Ọgbẹni James Ladiran ti o kọwe yin awọn arakunrin wa na ni ni nibo ni a gbe sinku iru ẹgbẹ Yoruba parapọ be ti a fi igba kan da silẹ ti a npe ni ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA si. Ibere ọrọ Ọkbẹ i wa na si awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ lọwọ.

Nitotọ o dabi ẹni wipe a ko ni ẹmi asape lati fi ṣe nkan yọri. Ọkanju ati ilara pẹlu awọn iwa buru, ku ti ọ so mọ wọn ki i jẹ ki a le gbe nkan doti. Ẹnu nikan ni a ni bi iya ti o nta akara lọja.

Bi a ko ba fẹ ki iya jẹ wa tọmọ tọmọ lẹhinwa ọla, o yẹ ki a wa ona ti a o gba sọwọ pọ, ti a o fi iwa ikorira, igberaga ọtẹ ati anikanjọpọn silẹ.

Ọpa agbeleka ni ọrọ awa Yoruba lẹhin loju. Ẹniti o ba leti ki o gbọ ṣugbọn bi a ba jọ rin nṣe ni o nṣe o nyẹ ni, ẹnikan ki jẹ awa de

# Oro Patipati...

Ninu ọrọ awa Eleti-Ọfẹ ninu ọsẹ ti o kọja, a fi ye ẹnyin ọkawe wa wipe ko si nkankan ti awọn ọkunrin nṣe ni aiye ode yi ti awọn obinrin ko le ṣe, ṣugbọn ... kan ti a ri gba lati ilu Benin nipa ikilọ kan ti ... Fidihẹ, Oloye Dennis Osadebay ṣe fun awọn ... n Ipinl agbedemeji Iwọ Orun wipe awọn obinrin ko gbọdọ da si ọrọ iṣelu mọ ya wa lẹnu pupọ.

Kini ba Ọgbẹni wa na debi ọrọ patipati bayi? Tabi o gbagbe wipe IBO AWỌN IYA wa nwọnyi ni o gbe de aye ti on wa loni? Ki a maṣe tan ara wa jẹ, on alara paapa mọ wipe ti on ba sọ iru ọrọ bẹ fun awọn obinrin Aba ati awọn ti Ẹnugu mọ Onitsha nwọ ko ni foju rere wo on.

Iru ọrọ patipati bayi a ko gbọdọ gbọ lẹnu awọn eṣelu wa mọ nitoripe ko ba oju mu rara, ẹtan ni a o ba nibẹ.

# Iwe Si Olotu

# Egbe Omo Oduduwa Da? Ara Wa

Emi ko si ninu awọn Yoruba ti nwọn nso wipe ko yẹ ki a da ẹgbẹ Yoruba Parapo silẹ ṣugbọn nibo a fidi Ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ti a da silẹ nijọsi ti si?

Gbogbo agbaiye ni nwọn gbọ nigbati a da ẹgbẹ na sile ni iwọn nkan bi ọdun mẹtadinlogun sẹhin ṣugbọn iwa tẹmbẹlẹkun, imọtara eni, ọkanjuwa ati ilara ko jẹki a gburo ẹgbẹ na mọ.

Awọn Ibo mọ nkan ti nwọn nṣe ni ọna igba igba, awa Yoruba nikan ni o ko mọ ọna ti a ngba lọ. A ko ni ẹmi ifarada rara, o fi igbera sanlẹ ti a mba kiri. Bi a ba fẹ ki awọn ọmọ wa ki o dara lẹhin ọla ki a mọ di ẹni ẹhin, o yẹ ki a tete roun ara wa wo, ki a pawada.

Mo kan saara si Dokita Akerele ati Dokita Adekoye Majekodunmi, awọn ọmọ yoruba ti nwọn ri bi nkan ti nlọ si, ti nwọn si ṣe paramu lati fẹ jẹki ẹni wa ko lati parapọ nitori ẹhin ọla.

Ẹyin ọmọ Yoruba ẹ dide ki ẹ hu oku Ẹgbẹ ọmọ Oduduwa jade nibikibi ti ẹ ba gbe sin in si.

Ọrọ mi niyi, Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,

Oke Bode, James Ladiran
Ibadan

Awọn itan na dun pupọ ju o si nkọ ni lọgbọn. O yẹ ki a ma yombo awọn enia wa ti nwọn sṭra wọn lati ma fi asiko wọn ko iwe akọsilẹ fun lilo wa.

Ọpọlọpọ awọn enia miran wa nisisiyi ti nwọn ni ẹbun ati oye iwe mimọ sugbọn nwọn ko lo wọn fun ọna ti o le wulo fun araiye ọpọlọ wọn iṣẹ Oṣelu ti nwọn yio ri owo ko jẹ ni nwọn mba kiri.

Ti o ba ri wọn ninu iṣẹ oṣelu kiṣe wipe nwọn fẹ fi tọkan tọkan sin awọn ara ilu Tabi melo ni awọn oṣelu yin onimoto kabiti kabiti ti nwọn kọ akọsilẹ ti yio wulo fun awọn ara ilẹ Nigeria lẹhinwa ọla?

Olotu, o yẹ ki a gbaruku ti awọn diẹ ninu wa ti a ba ti wipe nwọn gbinyanju ninu wọn ni Alufa E.A. Atilade yi gbe wa.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, iwaju ni ẹ o ma lọ

Emi ni

IFỌ A Ọladimeji

# Iwe Itan Alufa Atilade Dun

Olofa mo farabalẹ ọrọ iyanju ti Ọgbẹni S. Ayanọla gba yin wipe ki e tun mu ile itan aladun daradara lati inu iwe Alufa (Rev) E.A. Atilade fun wa gẹgẹbi ẹ ti nṣe nigba kan.

# Tani So Wipe Ala Kise?

Mo gba fun Ọgbẹni "Olofin'oto" ti o sọ ninu iwe yin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ ti o kọja ti o nfi ye wa wipe ala ti a ba la nṣe boya awa ni a ki ṣe akiyesi wọn nigbagbogbo

Nitotọ ni Olotu, emi ti ba orisirisi ala ni ọsan ati loru ti awọn ti wọn ṣe Nigbamiran mo le gbagbe nkan ti mo fi la ala ti mo ba ṣugbọn nigbamiran wọn ta si mi lokan Ṣe ... nkan ju ara wa lọ.

Ẹniti o ba ni ala kise a jọ wipe ... ni Oluware Olotu awọn miran ni awọn ki la ala rara ti awọn ba ... O jẹ nkan ti o ya mi lẹnu, mo si ro wipe iru awọn enia bẹ ni wọn nfi teratara sun.

Ile ọjọ kan ... mo ki emi ma la ala ri, mo fe gbagbe gegebi mo ti wi ni akoko Ẹniti o ba sun ti ko la ala ki o kiye si ara re nitoripe oluware ti di oku enia

Emi ni,

Mushin Ọmọge Alice Tọwọbọla

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Egun Ajolojo

Iku Ọgbẹni Ọjẹlade Gbamgbose, atọkun egun kan ti a npe ni 'AJOLOJO' ti o ṣẹlẹ ni ijarun jẹki nniran ilu Eko atijọ nigbati ẹru wa lara awọn agbalagba, ti awọn ọmọde ko ti gboye ninu irọ pipa, ti nwọn ko ti lọ si ile-ẹkọ ole jija. Ilu Eko dara nigbana, ẹru si wa lara awọn egungun ati awọn atọkun wọn.

Emi ọgọrin ọdun ni nwọn pe Ọjẹlade ti o ku na gbogbo ẹsẹ awọn ọjẹ ti o mbe l'Eko ati Ebute-Metta ni nwọn pe sibi isinku na ni Popo awọn Aguda tojude Gbamgbose. Ajolojo ma jo lẹrun, o dgba o ṣe, ma j'ọpun, ma j'ekolo nkan ti nwọn nje ni ajule ọrun ni ki o ma ba wọn jẹ.

## Ọye Oyinbo Tan

Mo gbo wipe lehin ọjọ mewa loni ẹnikẹni ko gbọdọ gba oye lati ilu ajoji mọ afi ti o ba jẹ ọmọluju awọn alamojuto Ijọba alailọba ti a ṣẹṣẹ bọ si yi. Ọrọ na wa di o dori akahin akara degun, nitoripe mo gbọ wipe ọpọlọpọ awọn enia kan ni nwọn ti mbẹbẹ fun awọn oye bi oye OBE., MBE., OLE., ỌLA., MOLA., ỌDẸ ati OWO pelu nkan bẹbẹ lọdọ awọn ijọba ijọba ajoji; awọn kan tilẹ ni awọn oye ti mo daruko yi kere si awọn pupọ, nwọn ni awọn oye bi CMG., KBE ati KOTO ni awọn nfẹ.

Rikiṣi pin, boya rikiṣi ṣẹṣẹ bẹrẹ ni emi Ayiluka ko mọ, ṣugbọn emi na nfẹ oye lati ilu Oyinbo; inu mi yio si dun ti aṣoju ijọba ilu Gẹsi ba le fi oye bi OWO ati ỌLA di mi ọla sugbọn nko fẹ oye tẹmbẹlẹkun.

## OmỌba Ọyekan

Ọrọ oye ti emi na nsọ wipe o kan mi jẹki nniran ọrẹ mi, Ọmọba Adeyinka Oyekan, ọmọ ọmọ ọmọ Ọba Dosunmu to lọ si ilu awọn oyinbo Czechosvakia ni ọsẹ yi. Mo gbọ wipe Ọmọba Adeyinka da ẹgbẹ kan silẹ ni ilu Eko niya ilu awọn Oyinbo Czecho ti mo darukọ yi. Ẹgbẹdọrẹ ni ẹgbẹ na kiṣe fun lati ṣelu rara. Ologbo pami pami o wọọ. Ọmọba Adeyin alọ a dara, a bọ a sunan o!

## omimi-Ejo

Mo gbọ wipe ọrẹ mi Ọgbẹni Festus Okotie-Eboh OMIMI-EJO, Minisita Alamajuto eto Inowo Ijọba Apapọse ko ni si nile ti a ba nṣe ajọyọ eto Ijọba alailọba nile yi, nitoripe o ti palẹmọ pẹlu iyawo rẹ lati lọ si Prague olu ilu Czechoslovakia lati lọ wo awọn oja orisirisi tinwọn fẹ fi pote si ilu na.

Emi Ayiluka ki Omimi-Ejo wipe ọkọ a refo ṣugbọn ki o jọwọ ki o maṣe tun tọwọ bọ iwe-gbese wa fun wa nilẹ yi mọ nitoripe mo gbọ wipe o ti tun ra kalamu (pen) tuntun ti yio mu lọwọ boya lilo le kan an lati si iwe adehun fun Ijọba ilẹ wa, bẹ ko si dara lati fi gbese ko ọmọ tuntun ti a fẹ bi jade Bi ẹ ko ba mọ, ọmọ tuntun ni eto Ijọba alailọba (Republic) ti a fẹ bọ si yi. Iyẹn bẹ.

## T O S Benson



T O S BENSON

Mo ki ọrẹ mi Oyolabi Benson ku abọ irin ajo ti o lọ lai pẹ yi, mo gbọ wipe o ri Pope Paul titun ti o ṣẹṣẹ gori oye sugbọn iyawo rẹ Opra nikan ni ku ... foju kan nitoripe obinrin ko gbọdọ lọ bi Pope n yẹwu ninu Afia wọn, o ni iṣẹdalẹ wọn ni. Iyẹn bẹ.

## Redio Nko?

Owolabi, kini o fa ọrọ redio wa fun agbara ti a fi owo iyebiye ṣe ti o di wipe nwọn ki gbọ ti o ba so ju ilu Ikorodu lọ? Mo gbọ wipe Ọgbẹni wa, Ọlọla Tafawa Balewa binu pupọ ninu irin ajo ti o lọ si Congo yi nitoripe ẹrọ redio ilu Nigeria ko fun awọn ara Congo ni irohin wa rara.

Ọlọla Ba'e a gbe redio lọwọ nigbati o nlo si irin ajo na ṣugbọn ẹrọ redio Ghana, Dahomey Liberia ati Congo ni o ngbọ ti nwọn nsọrọ kika ... ẹrọ Nigeria ku bamu bamu.

Emi Ayiluka paapa ti fi igba gbogbo dan ẹrọ redio wa na wo ni ilu Abẹokuta nko gbọ ọrọ lẹnu ẹrọ redio ilẹ Nigeria na. Awọn ara Ibadan ni awọn oṣiṣẹ ti nwọn so da sidi ẹrọ na nisisiyi ni nwọn ngbọ nkan ti o nsọ lọrọ pẹlu awọn ti nwọn ni redio ni ebute Ikorodu ati ni ita Iyalode Ikorodu ọrọ redio na ko ju bẹ lọ.

## 'Aiyekoto'



Mo ba ọrẹ mi Ọgbẹni Bisi Onabanjọ en ti gbogbo wa mọ adapọ oruko rẹ ni "AIYEKOTO" yọ fun bibọ ti o bọ ninu ihamọ pajawiri pẹlu ... ọrọ ti ko mọ mọwọ ti ko mẹṣẹ. Emi Ayiluka ba ọrẹ mi atijọ na yọ pupọ, a si wu mi ki mba a fẹsẹ kan dọ Ijẹbu fun sin idupẹ.

# Eleti-Ofe Daraba

# Olofintoto

(o bere ni oju ewe keta)

gba aga nidi awon.

Nitoto ko si eniti a o gbe gesin ti ko ni seipako luke. Awon kan ninu awon asoju ti a fi idibo yan sile igbimo ni awon ni lati wa nile igbimo fun odun mejewa ou... mewa kise odun ....

Boya Oloia Tafawa Balawa, ...akoso Ijoba Apapose le gbawa lowo eto pampa yi, ki a dibo lati ran awon enia miran lo s ile gbimo-asofin, iyen ni a ko le so.

## Egun Ko Mokan

Mo se alabapade awon kan ti ko mo irumo iru ijoba ti a fe bo si na laipe yi, nwon ni awon bo lowo Ijoba ko-sowo ko-sowo, awon ni bi eto Ijoba tuntun yi ba ti bo si awon yio ma te owo ti wa ni, ko ni wipe a ngbase lowo oba ajoji kan lati ma ro ouwo mo iyekiye ni a ro loj mo.

Awon baba Egun-komokan na ba mi jiyan titi de ibi wipe gbogbo awon adajo K tu ni yio palemo kuro ni ile Nigeria ko ni si Kotu ibile mo ati Kotu olopa. Nwon ni ti awon ba ti le le awon oyinbo lo gbogbo iwe ofin won ni awon yio kan ina si patapata.

## Ko Ye Won

Awon ti o wa nidi nkan ti nwon n.o opa-wahala ti o wa nidi Ijoba ko-si-oba yi ko fi ye awon ara ilu ni gbangba rara. Mo gbo w ... awon ara ipinle agbede meji Iwo Orun paapa ti n... lemo lati se oti-ogogoro fun ajoye eto Ijoba ko-si-Oba yi.

Awon ni ko ni wipe olopa nmu awon awon mo iye garawa ki garawa ti awon ba fe lo ni oti ogogoro ni awon le pon sile.

## Owo-Ori

Awon ti ko mo nkankan ni se awon Oyinbo yi ri nwon ko wahala ti owo-ori wo'lu, nwon si ni lati ko wahala ti owo-ori na lo ti nwon ba ti nlo si ilu won nitori..a awon nfe ki ojo aseye ijoba ko-si-Oba mo yi ki o tete de kiakia ki awon le ma se yala yala.

Awon ti ko fe san owo ori nikan ko Si ni on nyo lori oro na, awon obi ti nwon ni omo ni ilewe papa ni o dabi enipe alafia fe ba won lori iwe ile-eko ti nwon nyi papa lododun. Nwon ni eleyi ko ni si mo ni Yaba ati Ibadan ... Enugu ni nwon mo, yio ti te awon iwee ko yi.

## Olopa Ko Si ?

Ki a mu ti awon obi ti nwon nran omo lo si ile-eko ti nwon ro wipe aafani de ti awon om... won yio ma ri ise se de n... awon ... Olowo igann ... paapa i ndun nwon si ti npan enu sile lati ma fi re awon enia je lonakona.

Se eru Ijoba awon Oyinbo ni o ti mba won, iyen si fere kuro nibe na, bi o ba ti wu wa ni ao ma se Ijoba wa loku ti Oluku'uku nro loti eto Ijoba alailoba ti a fe bo si yi. Bi o ba wu baba onile ni o le bu owo ori ile re, ko si olopa ti yio mu mo.

Awon kan ni a ko ni gbe kotemilorun ejo lo si iwaju awon Oyinbo mo nitorina nkan ti a ba fe ni a le da Ijo. Oro re o, enyin alamojuto Ijoba wa e la eto Ijoba alailoba tuntun yi ki o je wa yekeyeke.

## Oga Adajo Ba Awon Oroju Loya Wa

EKO— "O ya mi lenu lati ri wipe opolopo enyin loya agbejoro ni e nse ilora pelu ise yin, ni gbagbogbo ni e nwa si kotu laigbe iwe-ejo ti nwon gba yin fun wo rara ki e to jade nile".

Oloia Adetokunbo Ademola; Oga gbogbo awon adajo ile Nigeria ni o soro yi fun okan ninu awon loya ti o gbejo kotemilorun kan lo siwaju re ninu ose 'yi nigbati loya na nwoke; ti o nwole; ti ko mo oro ti yio so.

Adajo Ademola ni on tun fi eyi se ikilo fun gbogbo awon loya oniroju ti nwon yole ki nwon ye gbejo wa siwaju on mo ti nwon ba ri wipe ise agbejoro su awon ki nwon lo wa ise miran se.

# O Da Bo



Obabinrin ilu Gesi wa ninu oyun nisisiyi, ko saye fun mo lati lo sihin, bo sohun a nse nkan agbaja kiri larin ilu ati lehin odi mo, awon ibatan re ni yio ma yan si iru ise be e. Aworan yi ni igba ti o yan Olola Duke ilu Kent, ati aya re lo si ilu Oke Uganda ni Ila Orun Afirika fun aseye kan.

# British Aid To Nigeria Tops £32 Million Now

LONDON — Recent agreements completed with Nigeria will bring the total amont of British aid made to the Federation since Independence to over £32 Million.

This is revealed in a special British Government Report on 'Aid to Developing Countries' just Published in London.

The Report notes that aid to Nigeria following Independence began with an agreement to provide a grant equal to Nigeria's allocation of Colonial Development and Welfare Funds which was then outstanding, together with a Commonwealth Assistance Loan of £12 million, to enable the completion of the five-year economic programme begun in 1956.

### Ahmadu Bello

Last year a gift of £5 millon was made by the British Government to finance construction of certain insructions of higher learning. Just over £2 million of this will be spent on the Ahmadu Bello University and the balance on teacher training colleges and techinical colleges and institutes in the regions.

A further Commonwealth Assistance Loan of £10 million is also being provided by the British Government towards Nigeria's 1962-1968 Development Plan. This loan is for such orders as the Nigeria Authorities wish to place in Britain in the first two years of Plan, for agreed capital projects. This loan has since been supplemented by another £1.5 millieon for the purchase of steel rails from Britain.

In addition to this total of £32 million, Britain has also offered to make substantial contribution towards the cost of building the Niger Dan.

## "Know Britain" Course For West Africans

LONDON- Six West African teachers are among some forty Commonwealth Bursars who have joined a course designed to introduce them to the British way of life as a preliminary to teacher training conrses in Britain.

Visiting speakers to the course, being held in London from September 16-23 and organised by the British Council, include Mrs. E. C Mee, Chief Inspector at Britain's Ministry of Education; Mr. John Burrows, Staff Lecturer at the University of London, and Mr. Gerald Gardiner, Q.C. The Commonwealth Bursars will also meet Sir Herbert Andrew, Permanent Secretary to the Ministry of Education.

Taking part are three teachers from Ghana, and one each from Nigeria, Sierra Leone and the Gambia. The Nigerian is Mr. W.M Omatson of Koko, Western Region, who is to study at the Reading of Institute of Education

## Bishop Of Accra Says:
## Desire For Church Union "Urgent",

LONDON—A united Church in a united Africa is the "deep and urgent" desire of all Christains in Africa, the Bishop of Accra, the Right Rev Richard Rosezeare, told the annual rally of the Accra Diocesan Association in London recently.

"You must surely know by now that movements in India, Pakisitan. and Ceylon towards Church union are for advanced" he told a large gathering of English clergy and lay people who support the Accra Diocese. "In Africa the pace is quickening very rapidly indeed. Seven diocess in Nigeria are expecting to go foward to a union with Methodists and Presbyterians wihin the next two year or so In Ghana we are only a few years behind them in a similar plan. In East Africa the same picture is emerging."

Bishop Roseveare compared activities with the "slow" progress being made towards union by the Church in Britain itself. He then explained the impetus behind the movement in Africa by saying As the new free Africa is born, so is the desire for a united Africa: and this is reflected in the Church in the desire for one holy and apostolic Church in Africa-visibly one—a desite both deed and urgent.



# Factory Of The Future

**This two-storey plastic building, which may be the forerunner of fabricated industrial buildings, was shown in Birmingham England, recently,**

# "A Ko Fe Owo Wahala"

YABA—Ni oru apa awọn ga ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ko fọju kan orun rara nibi Ipade ti nwọn se lori owo ti nwọn ni awọn fẹ ki awọn Ololu Ijọba Apapọse fi kun owo oṣọsu awọn.

Nwọn ni owo ijọgbọn ni owo ti nwọn ni ki awọn wa ya yi, awọn ni awọn ko fẹ owo wahala rara. Nwọn ni okankan ni awọn fẹ se ni ikilọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ awọn, nwọn ni awọn ko fẹ ki nwọn gba owo gbese na rara.

Nwọn ni awọn fẹ ki olukuluku awọn oṣiṣẹ yi duro de nkan ti awọn yio ba ṣe ni ọjọ marun loni; awọn ọga ẹgbẹ oṣiṣẹ yi ni awọn si wa lori ero ọna ti awọn yio gba lori owo ti awọn ọlọtu Ijọba ko fẹ fi kun owo oṣọṣu awọn yi.

Awọn oṣiṣẹ yi ni awọn mọ ọgọọn ti awọn alakoso Ijọba yi nda, nwọn ni nwọn tun fẹ torun awọn bọ gbese ni o.

## Gomina Azikiwe Goke Agba

(O bẹrẹ loju ewe kini)

dent) lọ aitoripe on ni o le yọ Prime Minister ati awọn adajọ kotu kuro lori aga wọn.

Lẹhin eyi nwọn tun fẹnu kan eto yiyan ti nwọn yio ma yan awọn adajọ Kotu. Awọn kan ni ko yẹ ki nwọn gbe ọrọ yiyan awọn adajọ kotu na le awọn oṣelu lọwọ, ki nwọn fi ọrọ a ngba adajọ sọnu iṣẹ le awọn igbimọ ti o ti yan wọn na lọwọ. Nwọn ni awọn ti nwọn yio ba fi ṣe adajọ ni lati jẹ ẹniti o nhuwa rere, ko gbọdọ jẹ enia patipati rara.

### Enia Kika

Awọn alakoso Ijọba ṣe ikede ninu ipade awọn igbimọ aṣofin wipe ọkẹ marundinladoje pọnun (£2.5 million) ni awọn a na lori awọn a'kọwe ti nwọn fẹ ka gbogbo enia ti nwọn mbẹ ni ilẹ Nigeria

Owo ti nwọn na lori awọn enia ti nwọn kọ ka ninu ọdun ti o lọ kọja to eyi rara. Ọjọ mẹta ni nwọn yio fi ka awọn enia na ninu oṣu November ti mbọ yi

# Nwon Yo Awon Ijoye Meta Kuro Nile Igbimo

IBADAN—A gbọ irohin wipe Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun pẹlu awọn alabadamọran rẹ yọ awọn ijoye meji pẹlu Ọba Iade kan kuro nile igbimọ awọn lọbalọba; awọn ijoye ti nwọn yọ kuro nile igbimọ na ni Ọloye Rotimi Williams, Apesin Itoku ni Abẹokuta, ọkan ninu awọn ogbogi lọya agbẹjọro ni Oloye Rotimi Williams.

Oloye keji ti nwọn yọ pẹlu rẹ ni Alhaji S. O. Gbadamọsi, Ọtun Ikorodu ati Ọba Samuel Akinsanya, Ọdẹmọ ilu Ishara ni Ijẹbu Rẹmọ.

O di ọdun mẹta gbako ti a ti yan awọn oloye si ijoko igbimọ awọn lọbalọba nigbati ina awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ (AG) si njo ni Ibadan.

# E Ka Oro Majekodunmi

lori Oro Egbe Yoruba Parapo

(loju ewe keji)



## Ara Ilu Nigeria ati Ghana

Aworan ti ẹ nwo yi ni ti awọn ọmọ ilẹ Nigeria ati Ghana ti nwọn nkọ iṣẹ bi a ti nkọle ni ilu Oyinbo. Ẹniti o wa ni apa osi yi ni ọmọ Ile ifẹ ti nwọn npe oruko rẹ ni Theo Amọo Omisore, ẹniti o wa ni apa ọtun ninu aworan na ni ọmọ Ghana kan, Ogbeni Frank S Amponsah-Bosompra lati Kumasi. Oyinbo ti o wa larin wọn ni o nfi iṣẹ han wọn.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 23370 Lagos; Editor (Olotu Ọ... Quatade, 15, Kosoko Street, Box 467, Lagos.